AKIYESI

Ẹ sare tete wa ra awọn ọja ti o ya nile wọnyi:- Cash and Rent Receipt 6s dozen, £2 15s gross, Calendar 1958, 4s 6d dozen, £2 8s gross, Gbedegbeyo Hausa £1 4s dozen, £12 8s gross, Goldsmith Receipt, complete set 17s 6d, ati orisirisi oja be.

Anie iwe fun Sosi, Ile-Iwe, Egbe ati bebe, ao te kinkia, yio si te yin lorun. E kowe si Manager:-

*Iyeru Press and Bookshop 68, Clifford Street, Ebute-Metta.*

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE

Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KẸTA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. I No. 36. MARCH 5, ~~FEBRUARY~~ — MARCH 11, 1958 KỌBỌ KAN

# Adelabu So Pe, On Ko Nse eni To Nba ebi-je

Ako mo idi ete, ati ero ti awon egbe N. C. N. C. ro ki nwon to yo opolopo awon omo Yoruba ti' o wa ninu egbe na. Sugbon nitori ki o ma ba si yegede, kotan nidi re, ni Ogbeni Adegoke Adelabu se lo da egbe ajumose Yoruba kan sile ti nwon npe ni 'Egbe Yoruba Parapo'



Nigẹrẹ ti oro di mimọ wipe awon Yoruba ti nwon yo kuro ninu egbe N. C. N. C. ti da egbe ara won sile ti o je pe okuru ọmọ Yoruba lo mbẹ ni inu ẹgbẹ na, nwọn kọwe ibaniyọ si Adelabu lati ba ẹgbẹ titun na yọ.

Ọgbẹni Adelabu sọ wipe dida ti da ẹgbẹ Yoruba Parapọ silẹ, on ko da silẹ wipe ki ẹnikan maṣe san owo ori.

Awọn kan fi ẹsun Adelabu wipe nitori ki awọn Yoruba to nṣe ẹgbẹ N. C, N. C. le kuro, lọ ṣe da ẹgbẹ na silẹ sugbọn Adelabu dahun pe, ọrọ ko jẹ bẹ, ibiti nwọn fi oju si, ọna ko jọ ibẹ.

## AWON OLOYE BA OBA ADELE PARI EDE AIYEDE

Dr. Akinọla Maja, Sir Kofo Abayọmi, Alhaja Rabiatu Iyalode, Ọgbẹni Sadiku Sarumi, Ọgbẹni Abudu Smith ati Dr. Akanni Doherty, awọn ti a fun ni oye ti wọn ko si fẹ di oloye mọ nitori ede aiyede ti o wa larin oloye Aminu Kọsọkọ ati ọba Adele ti pada si iga Idunganran lati di oloye pada.

Wọn si sọ ninu ọrọ wọn wipe, ninu oṣu December ọdun ti o kọja, ede aiyede ṣelẹ larin wa ati ọba Adele ti Eko lori yiyọ ijoye Aminu Kọsọkọ Aṣọjọn Ereko ti Eko kuro loye, nitori awa si ranri lati di oloye ti ọba Adele.

Ọlọla Alhaji Muhammadu Ribadu minista ohun gbogbo ti nlọ ni ilu Eko nfẹ ki a tete pari ija yi. Nipa ọla ọba Alaiyeluwa Alake ti Abẹokuta ati fenu si awọn ọba miran lati Iṣọ-Orun, a mu ede aiyede yi wa si opin patapata ni igbati a ṣe ipade ni Abẹokuta. Ijoye Aminu Kosọkọ si fori balẹ fun Ọba Adele, nipa eyi a si gba pada si ipo oye rẹ.

A si nfẹ ki gbogbo gbo mọ wipe awa na si ti gba ipo oye wa. A 'si wa pẹlu Ọba.

## AWON IWE KOSEMANI

Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Ẹsin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan a ti Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Iwe Itumọ Ala ati Ami Ara 3/6d
Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 2/6d

Akiyesi:- Ọpọlọpọ onibara wa ni ko mọ ile-iṣẹ wa ni Mushin, a fi eyi si eti igbọ wọn pe ki wọn ma lọ ra POSTAL ORDER ni POST OFFICE pẹlu Stamp 1/- ki wọn fi ranṣẹ si wa, nwọn yio si ri ọja wọn gba kiakia.

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

## Olori Ijoba Naijiria Wipe:

### E ra oja ti a se ni ilu Naijiria

Olori ijọba gbogbo ilẹ Naijiria Alhaji Abubarka Tafawa Balewa sọ wipe o ti jẹ aṣa ijọba oun lati ri wipe gbobgo gbo ni yio ra awọn ohun ti a nṣe ni ile Niajira. O sọ eyi nigbati o nṣe ifihan ni gbangba, gbogbo ọja ti a nṣe ni ilu Naijiria eyi ti si wa ni Racecourse lana ni Eko. Awọn ti nwọn ni ọwọ ninu si ọja ifihan ni gbangba yi ni awọn ile iṣẹ Commerce & Industry. Ile iṣẹ Posts & Telegraphs si ṣe ifihan ti wọn ni apakan-

Olori ijọba Naijiria si fi inudidun han nipa ṣiṣi ile ọja ifihan yi. O si wipe idi ifihan awọn ọja nigbangba ni lati mu awọn ti wọn nraja ati awọn ti nta papa, ki awọn ti nta si le ma ṣe si dada. Eyi yio si mu ki awọn ti nraja ni ọgbọn iraja si i.

Ifihan awọn ọja ti a nṣe ni Naijiria, ni lati mu awọn enia ra iru ọja bayi.

Ero ijọba si ni wipe awọn ile itaja nla yio gbiyanju lati ma ra awọn ọja ti "a se ni ilẹ Naijiria" wọnyi.

Ọba Adeniji Adele jẹ ọkan ninu awọn ti wọn wa si ibi ifihan yi.

Ṣaju eyi Governor General Ọgbẹni Oloye James Robertson ti wa ṣaju. Ninu ifihan awọn ọja yi ni ọpọlọpọ awọn ọja ti a nta ni ilu Nijiria.

Ojojumọ ni ṣiṣi ile ifihan ọja yi lati agogo mẹwa arọ di ago kan ọsan, ati lati agogo mẹrin titi di agogo meje. A o si pari ifihan yi ni ọjọ kẹjọ oṣu yi.

# IMỌLẸ

ẸSIN ORỌ WA:- IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos**

**Telephone: 21985**

*London Office:*

~~Sunday~~ *Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE

PUBLISHING DISTRIBUTING CO, LTD. MITRE HOUSE 177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN

**EKO**— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin ( 4/4d )

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa ( 6/6d )


## ENYIN MUSULUMI ORO E FI IMO SOKAN

Ko ni kun to bẹni ko si ni dun to ti awa oniwe Irohin Imọlẹ yi ko ba gbe awọn ọmọ ibilẹ Oro lẹsẹ nipa wahala wọn lori ọrọ edeaiyede ti o ti wa larin awọn apakan Musulumi Oro nitoripe o ti le ni oṣu mẹwa sehin ti awọn ọmọ ibilẹ Oro nkọ ọrọ sinu Iwe Irohin lorṣiriṣi ni ede Yoruba ati ni ede Oyinbo nipa pe ki ọrọ ija na ba le pari kiakia, ṣugbọn titi di oni a ko ti gbọ wipe ọrọ na ti pari tabi ko ti ipari?

Nitorina awa oniwe Irohin Imọlẹ ti gba imọran lati ẹnu awọn ti o jẹ ojọgbọn Ilu Ọro lati le sọ diẹ ṣoki ki a si fi ye yin wipe ija larin ẹlẹsin kanna larin ilu kanna ko tọ bẹni ko si yẹ fun ẹnyin agba tabi aṣaju ẹsin Ọlọrun ti o bajẹ wipe awọn ọmọyin ni o nja a bi yin lere kini ohun ti ẹnyin agba yi yio ṣe si lati pari rẹ, dajudaju pipe ni ẹo pe ti wọn ẹo si pari rẹ, mo si rope bakanna ni awọn ọmọ na si ti ṣe sẹhin ki o to di wipe nwọn bẹrẹ si kọ sinu iwe Irohin nigbagbogbo.

"Wọn ni agba ki wa ni arin ilu ki ori ọmọde pa toto o ṣe bi owe" Ẹ ma ṣe jẹ ki awọn ọmọ nyin wọnyi ti nwọn wa ni idalẹ kakiri ba ọkan jẹ nitori ija yi, ẹ jẹ ki ọkan wọn ki o ma fa ṣile nigbagbogbo ki ẹ si mọ daju pe Ile ni abọsimi oko. Ki ẹ mọ wipe ibikibi ti awọn ọmọ wọnyi ba lọ, ile ni nwọn ma fi abọ si, ti ija ba si wa larin enyin agba, dajudaju ori ko ni ya awọn ọmọ wọnyi lati ko ilana titun ti nwọn ri nibomiran wọ arin ilu nyin.

Haba, Ọlọrun ko ni dide tabi ki o sọkalẹ wa ba nyin sọrọ bikosepe ki o fi enia ṣe sababi nyin. Nitorina awa oniwe Imọlẹ kesi nyin gidigidi papa julọ ni aṣiko ti ẹ sẹṣẹ gba awẹ arugbo tan ti ẹ si npese ọkan nyin silẹ fun Awẹ gbogbo-gbo ti yio bẹrẹ laipe yi ẹ jẹ ki ori awọn ọmọ nyin gbogbo ti owa ni idalẹ kakiri ya si ati wale fun ọdun ki ọdun na si ni arinrin.

Lakotan a bẹ yin pupọ wipe ki ẹ jawọ kuro ninu apọn ti ko yọ, kakiri gbogbo agbaiye lode oni larin ẹsin ija ifẹ ni olukuluku nja, bawo ni tiyin yio se wa ri ti ko fi ni pari. A le fi ti Jesu se apejuwe fun nyin gẹgẹbi iya ti o jẹ lẹhin ti ẹnikẹni kan lẹse ti wọn tutọ si lara tan sibẹsibẹ o tun da wọn lohun wipe "Baba dariji wọn nitoriti nwọn ko mọ ohun ti nwọn nṣe, a rope iruẹ ọrọ bayi ni o tọ fun asaju ẹsin, aṣaju ẹsin gbọdọ gba iya ati ẹgbin.

Ẹ FI IMO SỌKAN ẸNYIN MUSULUMI ORO


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, Bamgbose Street, Lagos. Phone 21985


# Iwe Si Olotu

## E LA EYI YEMI

Jejẹnimojoko, Jejẹnimonlọ ati Jejẹnimoduro, awọn mẹtẹta nba ara wọn ja. Nigbati mo sare la wọn ni ija mo bere nkan ti o fa ija lọwọ wọn.

Ẹni kini rojọ o ni, jẹjẹ ni mo joko, ẹnikeji rojọ o ni jẹjẹ ni mo nlọ, ẹnikẹta ni jẹjẹ ni mo duro. Emi ti mo bere ọrọ lọwọ wọn ko wa mọ iru ẹsi ti mo le fun wọn.

Tani ẹ mọ pe o le kọ tọ ara wọn ninu awọn mẹtẹta? Tani ẹni ẹ ro pe o le kọkọ lọ finran si ara wọn?

2. Mo ni ọrẹ kan ti o jẹ ọrẹ mi pataki ti a jẹ korikosun, ti a jọ njẹ ti a jọ nmu, ni yan o lọ ba iyawo mi lopo, mo wa ka wọn mọbẹ, emi ko wamọ iru nkan ti mo le ṣe fun ọrẹ mi na.

Mo bẹ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ki ẹ la yemi o.

Emi ni,

R. A. T. Kọlawọle

Oke-Rimi.

---

Olotu Irohin Imọle jọwọ gbami laye lati le bere awọn ọrọ wọnyi lọwọ awọn ojọgbọn. (1) Ẹ la eyi yemi "Ẹniti o fun enia ni Ile lati ma gbe, pẹlu Ẹniti o ba enia wa ọna iṣẹ lati ma ṣe, pẹlu Ẹniti o fẹ Iyawo fun enia".

Ẹ la eyi yemi tani o ni lada ju?

(2) Ẹlẹkeji Ibere mi ni wipe, enia fẹ lo si ile anọ o lọ ya ẹwu ẹtu, nigbati o de ile anọ, o ni oru nmu on, o bọ ẹwu rẹ si ori ikọ, nibiti awọn anọ gbe nkọja lọ kọja bọ, wọn si ṣeṣi re ẹwu ẹtu na sinu epo. Ẹ la eyi yemi kinni o yẹ ki o ṣe nigbati ki ṣe wipe on lo ni ewu?

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, Ọkọ Ọba ko ni ba yin lẹsẹ.

Emi ni,

Suberu Owolarafẹ

---

E la eyi yewa ẹnyin musulumi, wipe ki obinrin ma ki irun ni Mọṣalasi tabi ko dara? A fẹ ki wọn fi ibi ti o ba wa ninu Quran tabi Adisi ki wọn fi han wa, nitoripe awa ko gbọ lẹnu awọn alfa nla ninu Iwọ wipe Anọbi nkirun pẹlu obinrin ni Mọṣalaṣi, wọn si ma nsọ wipe ti Anọbi ni awọn ri kọ iṣẹ, bẹ awa ko si gbọ wipe Anọbi nkiru pẹlu obinrin.

Mo dupẹ aye ti Olotu gba mi, Ọkọ ọba koni ṣa yin lẹsẹ.

Emi ni,

S. O. OKEYA

5, Idunmagbo Avenue,

Lagos, Nigeria.

---

Ejọ ibere kan ni mo fẹ bere ni ọwọ yin. Ti mo ba jẹ Kristẹni, ti mo ba ni iyawo kan, ti iyawo na ba bi ọmọ fun mi, ti owo ba wa ni ọwọ mi, ṣe mole fẹ omiran si?

Ibere mi ko ju bayi lọ o.

Emi ni,

David Boy Igeh.

---

Ibere ati idahun awọn ọrọ Mimọ Ọlọrun:- Kini on ti ẹ mọ nipa awọn ọrọ wọnyi, ati nibo ni a ti le ri nwọn ninu iwe Mimọ?

(1) Ni atetekọṣe Ọlọrun da ọrun on aiye.

(2) Ranti ọjọ isimi lati yasi mimọ.

(3) Bọwọ fun Baba on Iya rẹ.

(4) Ọmọ mi, bi awọn ẹlẹṣẹ ba ntan ọ iwọ ma ṣe gba.

(5) Iwọ ko gbọdọ ṣe ojukokoro si obinrin ẹnikeji rẹ.

Jọwọ tete fi idahun ibere rẹ ṣọwọ si:-

Idapọ Alufa Mujual Aid Association c/o P. O. Box 518, IBADAN.

---

Inu mi yio dun ti o ba gba mi laye lati ṣe ibere mi yi lọdọ awọn onkawe Irohin Imọlẹ. Ibere mi na niyi, kini idi rẹ ti awọn obinrin Imale ma fi nde fila ( cap ) ọkunrin, papa aṣa yi pọ lọwọ awọn obinrin Ibadan.

IBERE KEJI

Ọpọlọpọ awọn enia ni o ma nbu ara wọn pe yio ba Iya rẹ tabi yio ba baba rẹ. E jọwọ kini itunmọ ebu yi tabi kini nkanna ti yio ba Iya oluwa rẹ.

Mo dupẹ Olotu fun aye ti o gbami, ọkọ ọba koni ba ọ lẹsẹ Aṣẹ.

Emi ni,

Davids Oyelere Iṣọla

N.W.2/84 Ori Eru,

Ayẹyẹ Ibadan.

